# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORẸ AIYE TẸNI GBOGBO LAWA

No 1,424 MONDAY AUGUST 9, 1965 (2D)


## Ẹjọ Oloye Ọrẹdẹin Bẹrẹ Loni

IBADAN Ni deede agogo mẹfa irọlẹ ana ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹjọ oṣu yi awọn eni ti bẹrẹsi de si igboro ilu Ibadan lati Ijẹbu Ode ati agbegbe rẹ fun ẹjọ Oloye Samuel Taiwo Ọrẹdẹin akowe agba ẹgbẹ Afẹnifẹrẹ ati Alaiyeluwa Alfred Babingon Ashaye, Ọba Ologere ilu Ogere pẹlu awọn enia mejila miran ti Ijọba mba ṣe ẹjọ apania eyiti awọn fẹ ṣe ni Ibadan ni owurọ yi

Ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ keji oṣu yi ni awọn abanirojọ pataki fun Ijọba sọ ninu ile ẹjọ Ijẹbu-Ode wipe awọn ko ba awọn enia na ṣe ẹjọ mọ, adajọ ile ẹjọ na Ọgbẹni Oyemade si da awọn enia na silẹ, ṣugbọn bi awọn enia na ti fẹ jade ninu Kotu ni awọn Ọlọpa tun mu awọn enia na ti awọn si mu wọn lọ si Ibadan.

Nigbati o di ọjọ keji ni awọn ọlọpa tun mu awọn enia na lọ si ile ẹjọ ṣugbọn lẹhin ariyanjiyan diẹ ti o wa arin awọn agbẹjọro Ijọba ati awọn enia ti Ijọba nba ṣejọ adajọ ile ẹjọ na yẹ gbigbọ ẹjọ nasi owurọ yi ninu ile ẹjọ na ni Ibadan lati maa ṣe iwadi ọrọ na.

Ọgbẹni Olu Ayọọla sọ fun ile ẹjọ na wipe adajọ Ibadan ko ni aṣẹ lati gbọ ẹjọ Ijẹbu Ode nitoripe ile ẹjọ giga wa ni Ijẹbu Ode adajọ Ijẹbu Ode lo ni aṣẹ lati ṣe gbogbo ẹjọ ti oba ṣẹlẹ ni Ijẹbu Ode bẹẹni adajọ Ijẹbu-Ode na ko si tun ni aṣẹ lati ṣe ẹjọ ti o ba ṣẹlẹ ni Ibadan nitoripe adajọ wa ni Ibadan.

Oniwe Irohin wa Ejongboro ti olọ si Ibadan lati irọlẹ ana lati lọ gbọ bi ile ẹjọ na yio ti ṣe pari ẹjọ na si.

# ROGBODIYAN NLA TUN BẸSILẸ NINU ẸGBẸ DẸMỌ!

IBADAN:— Gbogbo ile lo kunṣọṣọ ti ẹṣẹ ko si gba ero ninu ipade awọn Oniwe Irohin eyiti awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ mẹwa kan ti nwọn tun jẹ Minista ninu Ile Igbimọ Asofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria pe ni ọjọ ọjọ'Bọ ti iṣe ọjọ karun oṣu yi ti nwọn si sọ fun gbogbo awọn Oniwe Irohin ti nwọn wa si ibi ipade na wipe, awọn lodi si gbogbo eto ti awọn kan ninu ẹgbẹ Dẹmọ nṣe nipa ibo ti nbọ yi.

Orukọ awọn enia mẹwẹwa na ni wọnyi:– Ọlọla J. O. Abiọshun, ẹniti iṣe ọmọ Ile Igbimọ na lati Iwo, Ọlọla A. S. Shonㅤotan lati Ibadan, I O Aniㅤvi, lati Iwo, J A Ajuwọn, lati Ibadan Ọlọla J A Adeyẹmọ, lati Oshogbo M A Adewunmi lati Ibadan, gbogbo awọn enia ti a darukọ wọnyi Minista ni gbogbo wọn jẹ ninu Ijọba ẹgbẹ Dẹmọ ni Ipinlẹ Iwọ Orun

Ọgbẹni D O Arowolo, lati Iwo I O Kẹhinde lati Ejigbo M A Adegbola lati Iwo, ati Ọgbẹni Fashọla.

Ninu alaye ti awọn enia na ṣe fun awọn Oniwe Irohin, nwọn ni ki iṣe wipe, awọn lodi si ẹgbẹ awọn, ṣugbọn ohunti awọn lodi si ni ọna ti awọn ọmọ ẹgbẹ na ngba nipa ọrọ ibo ti mbọ ni Ipinlẹ na nisisiyi ati ikede ti nwọn ṣe nipa rẹ wipe ki iṣe ohunti gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na jijọ mọ ti awọn si tun l'ọwọ si bi ko ṣe ohunti o wu awọn kan ni nwọn nṣe laiko jẹ ki awọn ọmọ ẹgbẹ yoku mọ nipa rẹ ti o si tun ba awọn ni ojiji ati aiko gbọ tẹlẹ.

Bakanna ẹwẹ, ni awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ na tun sọ wipe, awọn ko faramọ ọna ti awọn Ọba alaiye kan ngba lati maa ṣe ẹgbẹ Oselu ni Ipinlẹ na

Nwọn tilẹ tun sọ wipe, Ọba na ti sọ ọrọ ẹgbẹ oselu ohunti ko ni tan mọ atipe Ọba na ko mọ wipe, ọrọ ẹgbẹ Oselu ko lọ titi, bi ẹgbẹ kan ba lọ, ẹgbẹ Oselu miran si tun nbọ lọla.

Ṣugbọn bi awọn enia na ti ṣe sọrọ to ni ọjọ na nwọn ko darukọ Ọba kankan ninu gbagbo awọn Ọba Ipinlẹ na nigbati ọkan ninu awọn Oniwe Irohin si bere oruko Ọba na.

Ọkan ninu awọn Minista na ni "Oloye ni ọrọ nba wi, ẹniti ọrọ na kan, ti mọ ara rẹ, ọkan rẹ yio si tun maa jẹ ni ẹri pẹlu nibi yowu to o ba wa nisisiyi."

Gbogbo awọn Oniwe Irohin ni nwọn dawọ iwe kikọ wọn duro nigbati awọn enia na sọ wipe "Bawo ni awa ọmọ Yoruba ti ṣe le maa ṣa ara wa ti a ma a tun sọ wipe a nfẹ iṣọkan ati irẹpọ?"

"Iru iṣọkan wo ni a le sọ wipe a ni, nigbati awọn ọmọ Yoruba kan wa ninu ọgba ẹwọn ti awa kan nyọ naile ti a ko niran mọ,.

Bi a ko ba wa irẹpọ ati iṣọkan nkẹ, kini a a tun fẹ ṣe fun arawa ṣe e o maa lu ara wa pa larin ode ni ki gbo gbo aiye le ba mọ wipe a k ni ifẹ arawa?

Lẹhinna awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ na ni bi Yoruba ba fẹ ṣe ohun kan fun irẹpọ ati iṣọkan ni asiko yi gbogbo awọn ọmọ Yoruba ti nwọn wa ninu ọgba ẹwọn gbọdọ jade ki awọn ti nwọn jẹ olori ati aṣiwaju ninu wọn tun pada si arin wa ki nwọn si tun maa ba iṣẹ olori ati asiwaju wọn lọ

Nigbayi ni gbogbo aiye yio to le mọ wipe ni tootọ ni awa ọmọ Yoruba ni nfẹ irẹpọ ati iṣọkan larin ara wọn.

Nwọn wa kilọ fun Ọba na wipe ki o lọ mọ loni daju wipe aye ti o wa loni o le ma si mọ ni ọla atipe ki o ma jẹki wiwa ni ọgba ẹwọn awọn ọmọ Yoruba kan jẹ idunnu fun un ki o tun maa ranti ni gbogbo igba wipe "Ti ẹniti o de ni a ri a lo mọ ti ẹniti nbọ lẹhin ọla oni lari Ọba lo ke lo mọ ọla.

Onirohin wa ni Ibadan fi ye wa wipe ti tilẹ fi ṣu ni ọna ni awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ fi nṣe ipade ninu ile Oloye Akintọla ni Ibadan ni ana nwọn kosi gba ẹni kankan laye lati wọ inu ile na lọ ba wọn ṣe ipade na

Onirohin na fi yewa wipe awọn ko gba awọn ọmọ ẹgbẹ Alaku kọ ti nwọn wa ninu ẹgbẹ Dẹmo laye lati ba won ṣe ipade na la na awon ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ nikan ni nwọn ṣe ipade na,

Irohin na tun ṣe afikun wipe, awọn omọ ẹgbẹ Dẹmo ti da si ona meji nisisiyi awon kan wa lẹhin Oloye Akintọla awon kan si wa da duro gedegbe.

Ṣugbon Ọgbẹni Bọla Ige akowe Ipolowo WO OJU EWE KẸFA



Oloye S. L. Akintola
Olori Ẹgbẹ Dẹmọ

# SHOYINKA TUN GBE DE!

Fun isegun Aiye ati awon abatenije ra

## Turari Isegun Agba

10s 6d pangolo 2s 6d paketi



J. O. Shoyinka

Fun Iwosan gidi ati ibolowo aiye, Abiku, aita oja ra

## ☆ Iwe ilana ifa yanrin tite ati etutu sise 20s

Fun Isegun ota ile, ode, awon Agba ati adura Ajebidan ra

# IWEAFOSE

Isedale Yoruba ati

# PSALM

Ajebidan 3s 6d pere

*Fun itumo ijinle ala ati iwadi nkan nipa ona 'IFA' pelu ogun Ajebidan lati owo Josefu Alala ra*

## Iwe Itumo Ala ( Josefu Alala )

*3s eyo 25s dosin.*

*anta awon orisirisi iwe Egbogi miran bi*

## *Iwe Egbogi Awogba Arun 20s*

AKIYESI: ENIKENI TI O BA RA NINU IWE YI YIO GBA PAKETI TURARI ADURA LOFE'

**SHOYINKA** 9, Iyalla Street, Mushin.

## Ẹgbẹ Awo Pioneers Sọ Pe:
# EGBE UPGA NI YIO BORI IBO IWỌ ORUN

EKO:- Ninu irohin kan to de ile iṣẹ wa lati ọwọ Akọwe ipolowo ẹgbẹ Awo National Pioneers ti ilu Eko ati agbegbe rẹ, Ọgbẹni Sheu Adeshanu fi ye wa pe ko si ọna eru ti ẹgbẹ Dẹmo ti Oloye S. L. Akintola le gba silẹ ki ẹgbẹ Afenifere ma bori ibo si ile Igbimọ aṣofin Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria to mbọ yi.

Awọn ọmọ ẹgbẹ ni tun ṣe alaye pe kosi ninu awọn enia ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ti ko mọ ore nla ti Ijọba ti ẹgbẹ Afenifere ṣe akoso re tẹlẹ ṣe fun wọn. Awọn ọmọ ẹgbẹ na tun ṣe alaye pe gbogbo enia ipinlẹ na ti o jẹ olowo ati mekunnu lo nkan saara si Ijọba ti olori ẹgbẹ Afenifẹre Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ to ṣe Akoso re.

Ninu ipade kan ti Ọgbẹni Timothy Oluyedi ti iṣe akọwe idasile ẹgbẹ na ba awọn ọmọ ẹgbẹ wọn ṣe Surulere ninu ọsẹ to koja lọyi ni o ti rọ awọn ọmọ ẹgbẹ na lati duro gbọin gbọin lẹhin ẹgbẹ Afẹnifere o tun ke si awọn Ọba ati Ijoye ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati lọsọ ra gidigidi ki nwọn mase jẹ ki awọn ẹgbẹ Dẹmo ti iṣe ẹgbẹ odalẹ maa lo wọn gẹgẹbi ohun elo fun ẹgbẹ oṣelu.

Ọgbẹni Oluyedi tun kesi awọn Agbẹ ati awọn Oniṣowo lati ni Igbẹkẹle to daju pe wọn ba le dibo fun ẹgbẹ UPGA ninu Ito to mbọ yi o ni gbogbo ohun ti ko ti lọ deede ni yio ni Ilọsiwaju ati Idagbasoke yio wa fun olukuluku ninu iṣẹ wọn. O ni ki awọn Agbẹ Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria duro gbọin gbọin lẹhin ẹgbẹ Afẹnifẹre ki wọn si di Ibo won fun egbe na lasiko Idibo si ile Igbimọ aso fin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria to mbọ yi.

Ninu irohin awọn ọmọ ẹgbẹ Awo National Brigade ni nwọn ti ṣe Ikede pe awọn ọmọ ẹgbẹ na yio ṣe ajọdun wọn kini ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu yi ni Olu ile iṣẹ ẹgbẹ Afẹnifẹre ni nomba 214, Broad Street, Eko. Ipade ajọdun awọn ọmọ ẹgbẹ na yio bẹrẹ ni deede agogo mẹwa owurọ ọjọ na

## YE IRAWỌ RE WO

AQUARIUS (Jan - 22 Feb, 20) Ayọ ni fun ọ ni gbo gbo ọjọ oni pẹlu ara lile ti ko si ohun kan lati damu rẹ

PISCES (Feb. 21 Mar. 20) Tun gbogbo nkan ti o ti nṣe bẹrẹ ni irin ọna ti awọn enia yio fi ma ṣọrọ rẹ yio si dara fun ọ.

ARIES (Mar 21 April 20) Mase fi ọwọ'le ohun ti tun kan ti iwọ ko ṣe ri ero ti nwọn ngba ṣi ọ ni pe ki a le fun ọ lọrun.

TAURUS (April 21 May 20) Aisan kekere kan yio ba ọjẹ ṣugbọn alafia yio de ki o to to asalẹ.

GEMINI (May 21 July) 21 Maṣe lọ fi ọwọ fa ijọgbon wa ba ara rẹ jẹki o di gbati ilẹ ba su ki o ma ba sina,

CANCER (June 22 July 22) O ni lati wa akoko pataki lati fi wa iṣẹ ṣe loni iwọ yio si ri iṣẹ ṣe.

LEO (July 23 Aug, 22 Tẹlẹtẹlẹ gbogbo nkan dunia ni ko njo o loju ṣugbọn mase ṣe iro rẹ loni

VIRGO (Aug 23 Sept 23 Iwọ le ti oju rere ọrẹ rẹ gba tobe ti iwọ yo ni gbagbe ore na ti o se fun lailai.

LIBARA (Sept 24 Oct 23 Obinrin gbajumọ kan yio ba ọ ṣọrọ fifẹ a si ẹni bi o ba mura si ọrọ na yio di iyawo rẹ.

SCORPIO (Oct 24 Nov 22 Iturere rẹ si awọn enia yio mu ọpọlọpọ ire ati owo wa fun o.

SAGITTARUS Nov 23 Dec 21 Maṣe ba ẹni kan sọrọ asiri ki nwọn ma ba ṣe ofofo rẹ pe irin.


BERE EGBOGI ARỌN

# VERMZYN

Olulowo egbogi atamatase ti o daju fun iparun awọn "ARỌN" buruku gbogbo lara enia, papa tabi ni pataki fun ARỌN latanlatan tabi arọn kinisa ti o ma mu idiwọ wa fun ẹgbagbeje obinrin lati loyun tabi ti o ma'nba oyun jẹ lara Obinrin.




Bẹẹ si ni egbogi yi dara fun gbogbo ẹniti ara aibadu Igba aya, ọna ọfun, sisẹ lẹhin bi ake tabi aran oju pẹlu Meji irufẹ egbogi arọn yi kosi ni gbogbo ilẹ Naijiria ja Işẹ rẹ si daju.

AKIYESI PATAKI

Ri daju wipe o ti re eekọnọ ọwọ ati ẹsẹ rẹ daradara ki oto lo egbogi arọn yi gẹgẹbi awọn Jaman ti o ṣe ti juwe lilo rẹ o, Fun agbalagba nikan ni o wa fun. Bere orişiri egbogi arọn fun ọmọde pẹlu wọn nbẹ fun tita ni ṣọbu awọn:-

NIGERIAN MEDICINE STORES
4 Tinubu Square, Lagos
Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street Lagos



# EGBOGI JEDIJEDI

Aworan ẹgbẹ yi fi han gba ngba ibiti jẹdijẹdi to wa lara rẹ ti nyọ ọ lẹnu nigbagbogbo Ibẹ ni a npe ni omusu tabi iho idi enia Ibiti ẹ ma ngba iṣe igbọnsẹ Arun Jẹdijẹdi jẹ ikan ninu amodi ti o buru, ni pataki fun okunrin ti o si ṣoro pupo lati ṣe iwosan rẹ tan patapata.

Ọpolopo egbogi li owa tia nta kakiri ode isisiyi ti nwọn nna apolowo nwọn fun iwosan re ṣugbọn boyan ni a le ri mẹwa nin awọn ogun to le ṣe iwosan arun na daradara.



CYCLOVEN

Awọn elomiran lero wipe boya bi wọn gbe lo si ile iwo san lati lo ge eyiti o ba nyo jade ni omusu won nipa bẹ awọn yio bọ lọwọ rẹ patapata.

Ṣugbọn awa koro bẹ rara lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun bẹrẹ bakanna Orişirişi Jẹdijẹdi ni o wa Ekini ti o bẹrẹ aiko maṣe igbọnsẹ deede tabi lojojumọ, gigun kẹkẹ ologere Basikulu pupọ ẹ'omiran ẹwa ẹran Suga oniruru ohun adidun pupọ, pupọju nigba kugbi jẹdijẹdi orisirisi ni o wa ewo ni tirẹ? Bi o nyo sode ninu omusu tabi ti o ma nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnşe tabi ti nrin o ninu omusu rẹ ti o ba jẹ bẹ bere egbogi CYCOVEN ti awọn Oyinbo Jamani sese wa idi re ki o si dan wo o ri daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijẹdi patapata ti a ta nigboro Naijiria bere ni:-

WATERLOO MEDICINE STORE
8, Palm Church Street Lagos
Phone; 22878 Nigeria, Ọja Ita Faji

# Awọn Kan Fẹ Rọ Ọba Akarigbo L'Oye

SHAGAMU:- Ninu irohin kan to de ọwọ wa ni a ti gbọ pe awọn Ijoye ati awọn Oshugbo ti nwọn to mẹtalelogbon (33) ti ngberoṣlati ro Ọba Moses Awolsi Akarigbo ti Ijẹbu Rẹmọ kuro lori oye.



**Ọba Moses Awolesi**
Akarigbo Ijẹbu Rẹmọ

Ninu irohin na ti o de ọwọ wa la ti ilu Shagamu ni awọn ijoye ati oṣhugbo ilu Shagamu tisope Ọba Moses Awolesi Akarigbo ti Ijẹbu Remo kuna lati tele eto ofin ti awon igbimo Ọba ipinle Iwo Orun ṣe lasiko ti won npati ija kan fun Ọba pẹlu awon Ijoye na ninu odun yi ati pe ki Ọba na da owo kan pa da fun Ijoba ibilẹ Ijẹbu-Rẹmọ ati pe Ọba na tun kuna lati ṣe eto ilẹ to yẹ ki o ṣe ni ilu Shagamu.

Awon Ijoye pẹlu Oshugbo mẹtalelogbon na tun ṣe alaye ninu iwe ti nwon ti nwon ti ko si oba Akarigbo ni nwon ti ṣe alaye pe laijẹ wipe Ọba na tele eto ofin ti awon Igbimo awon Ọba ipinlẹ Iwo Orun ṣe ni Gbongan ti nwon npe ni Western Hall, Agodi, Ibadan, ninu ibẹrẹ odun yi ni awon Ijoye pẹlu Oshugbo ti so fun Ọba na pe awon fun un ni ogoji ojo lati lo ṣe eto na tabi pe ki o kuro lori oye rẹ gẹgẹbi Ọba ilu Shagamu.

Ninu imọ ti awọn ijoye na gbe jade lati ro Ọba na loye jade ninu ipade kan ti awọn ijoye mẹtalelogbon na ṣe laipẹ eyiti awọn ijoye ati ti Oloye Emmanuel Banjọ ṣe olori won ni wọn ti sọ laipẹ pe laijẹ wipe Ọba Moses Awolesi Akarigbo Ijẹbu Rẹmọ kuro lati ipẹlẹ eto ti wọn fi lelẹ fun Ọba na nwọn ki o yara te te fi aye rẹ silẹ gẹgẹbi Ọba fun ilu Shagamu ati paapa fun ẹkun Ijẹbu Rẹmọ.

Irohin tun fi ye wa labẹlẹ pe awon ijoye nati kọ we kan si minista alamojuto eto oye fun ijọba ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria Oloye Saka Layọnu lati yara rọ Ọba Moses Awolesi kuro lori oye gẹgẹbi Ọba Ijẹbu-Rẹmọ ki o to to ogoji ọjọ.

Nigbati oniwe irohin wa to wa ni Ibadan lọ si ile iṣẹ minista alamojuto eto oye fun ijọba ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati wadi ọrọ na lẹnu rẹ ni o ti ṣe alaye pe on ko ri minista na nile iṣẹ rẹ rara.

Oniwe irohin wa ni ilu Shagamu tuuṣe alaye pe on ko tun ri akọwe awọn ijoye mẹtalelogbọn ti nwọn fẹ rọ Ọba na kuro lori lati wadi ọrọ na lẹnu rẹ ni o ṣe alaye pe on ko ri akọwe awọn ọjọ na.


EGBOGI AWỌN ILU FARANSE

**TESSYDRE**

Fun Ọmọ—Ọwọ ati Ọmọde gbogbo



Tessydre jẹ ojulowo egbogi hauuhauu ti meji iru fẹ bọ kosi kakiri igboro ilu Naijiria fun itọju ọmọ ọwọ ati ọmọde lati le jẹ ki wọn ma hu ẸHIN ẹnu wọn pẹlu irọrun laisi wahala rara tabi aiko le sun yala lọsan fun awọn iya wọn gbogbo Ọgọrun orişirişi egbogi bayi ni wọn npolowo sinu ẹrọ gbohungbohun ati sinu iwe kika lojojumo şugbọn ko si eyikan le fi we egbogi Tessydre rara o, Ọlọgbọn di ori ẹja mu pupọ ninu awon ara ilu Saro ati awọn Agọnyin (GHANA) mọ egbogi yi dajudaju on ni awọn si nlo fun awọn ọmọ ti wọn ba şeşẹ bi titi fi di nkan bi ọmọ ọdun mẹwa gbako. Kosi wahala tabi iyọnu inu rirun ọsa ori aiperi ori inu iwọ osi fẹkun fẹkun ewo, kokoro ara lapalapa ara gbigbona igbẹ şişan gburu tabi aikolokun ninu ara, sisu inu kun nun aiorun ati orisirisi awon amodi tabi aisan ti o ma evọ awon ọmọ ọwọ lẹnu nigba Ehin HIHU gbogbo Tessydre a ma mu ki ehin ẹnu ọmọ rẹ lagbara gidigidi ati san pẹlu.

Awọn omo ti o nlo egbogi yi ki saba ma şa rẹ rara tiwọn igbati nwon ba ti nlo deede, ti otutu ki si le ri ayọ ati dara ni igbaiye wọn ti wọn nju un daradara nwon sun gbadun pẹlu yi si jẹ ki erigi san pẹlu.

NIGERIAN MEDICINE STORE
4 Tinubu Square Lagos


## E Ma a Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ

# IROHIN IMOLE

*IMOLE ORE AIYE TEN GBOGBO LAWA*

No. 1,424 MONDAY AUGUST 9, 1965 (2D)


## OGBẸNI COKER DI OlOYE

EKO: Irohin ko to afojuba ni ayeye inawo Iwuye ti Ọgbẹni Adeniyi Coker, ọkan ninu awọn Ọga agba ile iṣẹ Ijọba Ibilẹ Eko ṣe ninu Iga Idunganran nigbati Alaiyeluwa Adeyinka Oyekan Keji, Ọba ilu Eko fi njawe Oye le Coker lori ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ keje oṣu yi.

Irohin fi ye wa wipe, lati bi ọjọ mẹrin sẹhin wa ni gbogbo awọn enia, ẹbi, ọrẹ, ati gbogbo awọn oṣiṣẹ ninu ile iṣẹ Ijọba Ibilẹ Eko ti nrọ lọ sinu ile Oloye na lati maa lọ ba palẹmọ ti ayeye Iwuyẹ na.

Nigbati ọjọ Iwuye na si to, gbogbo awọn enia na ni nwọn ba Oloye na lọ sinu Iga Idunganran nibiti Ọba ti de Fila Oye fun un

Lẹhinti nwọn jẹ oye na tan ni gbogbo awọn alabaṣeyẹ ọjọ na wa bẹrẹsi jo, lati inu Iga Idunganran titi de inu ile Oloye na, ti awọn enia na si ṣere titi ilẹ ọjọ keji fi mọ kedere.

Ẹ o ma a ri aworan Oloye Coker na ninu iwe Irohin wa ni ọla. Awa Oniwe Irohin Imọlẹ ki oloye Coker wipe, o ku orire, ki Ade pẹ lori ki bata pẹ lẹsẹ. Ọkọ Ọba ko ni sa nyin lẹsẹ, o.

# ROGBODIYAN NLA TUN BẸSILẸ NINU ẸGBẸ DẸMỌ

LATI OJU EWE KINI

ẹgbẹ Afẹnifẹre sọ ni Ibadan ni opin ọsẹ ti o kọja lọ yi wipe, ede aiyede kan ti bẹsilẹ larin Oloye Fani-Kayọde ati Oloye Akintọla eyiti o nja ni abẹlẹ lọwọ bayi ti awọn mejeeji ko si fẹ gba ọrọ si ara wọn lẹnu mọ.

Ọgbẹni Bọla Ige tun gbe ọrọ rẹ lẹsẹ pẹlu wipe, nitori edeaiye de ti owa larin Akintọla ati Fani-Kayọ ni ko ṣe jẹki Oloye Akintọla le lọ si Ipade Aje eyiti gbogbo awọn Alakoso Ijọba Naijiria ṣe ni Ẹnugun ninu ọsẹ ti o kọja lọ yi.

Alhaji Tafawa Balewa, Alhaji Ahmadu Bello, Dọkita Michael Okpara ati Oloye Osadebay ni nwọn lọ si Ipade na, ṣugbọn gẹgẹbi alaye Ọgbẹni Bọla Ige, olo ye Akintọla nikan ni ko lọ si ipade na ninu awọn Alakoso Ijọba.

O wa kesi Akintọla pe ki o sọ fun gbogbo aiye gbọ bi o ba jẹ wipe irọ ni ọrọ ti on sọ yi.

Awọn ọmọ ẹgbẹ Ọdọ Afẹnifẹre ti kesi gbogbo awọn omo Ibadan wipe ki nwon tete yara ninu ẹgbẹ na nisisiyi ki nwon si darapomọ ẹgbẹ Afẹnifẹre nibiti nwon ti kuro tẹlẹ.

Awọn omo ẹgbẹ na tun so ninu oro won wipe 'Ida rudapo ti de sinu ẹgbẹ Dẹmọ nisisiyi, nitoripe asiko ibo ti de, asiri ẹgbẹ na yio si tun laipẹ yi fun gbogbo araiye ri, bi nwon fẹ bi nwon ko si fẹ."

Ni ipari oro awon omo Ile Igbimo Asofin Ijoba Ipinlẹ Iwọ Orun na fun awon oniwe Irohin ni Ibadan, nwon ni Ipinlẹ Iwo Orun Naijiria ni o ti jẹ olori ati Asiwaju fun gbogbo awon Ipinlẹ yoku ri, ṣugbon nisisiyi, awon omo ẹgbe na ni Ipinle Iwo Orun lo wa di ẹhinti o rehin ju lo ni Naijiria loni yi.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na tun ṣe pẹlu wipe, A ti ṣe iwọn ti a lọ ṣe lati gbẹ ẹgbẹ Dẹmọ ni igbọ nwọn ni Iwọ-Orun, a ko si le ṣe ju eyiti a ṣe yi lọ...

Bi a si ti nṣe to na gbogbo tun nbajẹ sii ni, dido wipe ki o ma a dara o tun nquru sii ni.


SUNSTAR DENTAL CREAM

**Onişegun Itoju Ehin**

JẸKI FIFỌ EHIN RẸ JẸ IGBADUN FUN Ọ

SUNSTAR nṣe orişirişi işẹ iyanu miran yatọ si pe,o ngmu ẹnu titu-yọyọ, ki o si ladun fun itọwo nkan gbogbo. Egbogi PROTEASE wa ninu ọrẹ yiti o nṣe iranlọwọ fun egbogi na lati de gbogbokọrọ ehin re ti o ṣoro lati de. a si jeki nwọn fun fun gbo o




Egbogi HEXACHLOROPHENE ti o si wa ninu gegebi apakokoro, yio dabo bo awọn ehin re nwọn ma le dipeta.

Ẹ le ri gbajumo egbogi SUNSTAR ifọyin ni gbogbo ile-itaja Egbogi yika Naijiria


## Abajade Orire Ijoba Iwọ Orun Naijiria

IBADAN Ni deede agogo mẹta ọsan ojo Abamẹta ti iṣe ọjọ keji oṣu yi ni Irohin de si iṣẹ wa lati Ibada wipe, abayọri idije orire eyiti nwọn ta ni Gbọngan Oke-Mapo-Ibadan ti jade ati wipe, ẹniti o ni nọmba B006929 ni o ṣe orire ipo kini ninu orire Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ti nwọn ta kọja lọ yi, oluwarẹ si jẹ ẹgbẹdogun Pọnun (£3,00)

Ẹniti o nọmba C 003284 ni o ṣe orire ipo keji, ti o si jẹ ẹgbẹrun pọnun (£1,00)

Ẹniti o ṣe orire tio gba ipo kẹta ni o ni nọmba B 002364, o si jẹ ẹdẹgbẹta Pọnun (£500)

Awọn enia marun miran ni awọn na tun ṣe orire ti ti nwọn si ọgọrun Pọnun (£100) ẹnikọọkan ni wọnyi;

F002433; C 600897; B009332 M007597.

Nọmba awọn adọta enia mian ti nwọn ṣe orire ti nwọn jẹ Pọnun mẹwa mẹwa ẹnikọọkan ni wọnyi:

F002433, C006897, Koo 9836. B009332 M007597. 60 PRIZES OF £10 EACH H003787. C009446' C00 6504. C009626. F001323 D005975 H008703. K002221. G003294 C007358. J008396. K001119 D002737 E0048751, E004851. E005968. 1005384 F009605 G005550 G009885 B005813 N001171 F008337 L009584 I008107 F009996 E0005127 C004034 K000975 E003855. C001859; E004054 F006768, E006424 L005988, F009408, H008245 I006094. E001011, B005187 A007607, C004319 H000747, C005756 F004189 K005280 J007494 C004427 N005557 E006562. L007991.

Nọmba awọn ọgọrun enia miran ni nwọn tun ṣe orire ti nwọn si jẹ pọnun marun - marun (£5 each) ẹnikọọkan ni wọnyi:-

100 PRIZES OF £5 Each

G002898, J007998 B008518, A007184, F001981, H006345, B004521, B002050, 1002437, D005410, N006724, M003179 A002609, E008836, A000874, M008488, C007092 M008900, B003264, C005069 B009424, C006075, H05589, C008997, K003681 H004060, C007570, F000488, Dooo125, Eoo5585, Coo7741, Moo1647 Moo7589, Aoo129o, Eoo7741, Boo9786, Moo858o, Ioo6269, Kco1719, Eoo8227, Joo6242, Foo356o, Noo7813 Aooo8o7 Joo 44o2 Coo6454, Eoo4996 Foo2923, Doo8478 Aoo4642 Aoo411o Aoo6529 Moo8251 Doo2378.

Goo6o77 I0035o6 A008217 G004808 F007211 I008289 G007651 H009587, N002677, B009251 C002238 N006164 B005453 F001484 B003950 M008444 B002219 H003006 C008684 G007742 F008133, DOO5445. MOO2850, IOO9467 BOO8241, LOO7042 AOO9615. HOO1773 DOO9207 BOO5400, DOO7887 FOO3684 EOO6538. EOO5671, IOO1542 EOOO956, FOOO970, BOO4530 LOO4043 KOO7139. KOO2858 MOO2931, IOO5323, KOO5645 FOO7747.


Printed & Published by Modune Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos, Phone 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street Lagos 9/8/65